**Owe**

Ọpẹ Ijaiye ni ki a bi lere ogun Ogunmọla, A k i n i, njẹ akini, afi ni han ajẹ afi ni ban, owo m ti oku ara Ibadan lojude Ṣodẹkẹ. Ọniọ ti Gambari ba bi, okun ni yio kọ, abọ ọrọ to f u n ọ m ọ luwabi.

# IROHIN IMỌLẸ

MOTTO: IMỌLẸ-DE, OKUNKUN PARADA.

**LAKAYE ORO**

Ọlọgbọn ko le ta koko Omi si eti aṣọ bẹni ọmọran kole mọ Iye erupẹ ilẹ, Irọ lo npa irọ fun irọ, Alagbadẹ ko le rọ Ike, Ṣigidi ti ko lẹnu ni, on lẹ sọrọ, ẹ o ri wipe irọ lo npa irọ fun irọ. I r ọ ni Babalawo npa, ko gbọ ifa.

VOL. V No. 384 MONDAY NOVEMBER 6 — NOVEMBER 12 1961 KỌBỌ MEJI (2d

# Oloye Awolọwọ sọ oju abẹ niko, awọn Oṣelu Suraki

EKO:— OHUN TI OLOYE AWOLỌWỌ SI PAYA HAN AWỌN ONIWE IROHIN NI WIPE, AWỌN ENIA NFE KI WỌN MA ṢIṢE DIẸ, KI NWỌN SI MA GBA OWO JABURATA, ṢUGBỌN NISISIYI OTITỌ DE OJA O KUTA, ṢUGBỌN OWO NLA JABURATA NI NWỌN NRA EKE.

Ogunlọgọ awọn enia lo nsare wọ iṣẹ Iṣelu. wọn fi nhan enia wipe, bi enia ba ti ko si iṣẹ Oṣelu, bi ko tilẹ ri iṣẹ ṣe, yio ma mu owo wa fun oluwarẹ, oluwarẹ si le gba ibẹ di olowo, owo ti awọn enia ba dajọ si ọwọ iru awọn enia bẹ ni lati fi ṣe nkan a tata, o di ki iru awọn ẹni bẹ, bẹrẹ si na jẹ funra rẹ.



OLOYE ỌBAFẸMI AWOLỌWỌ

Iru awọn Oṣelu bayi, ti nwọn npurọ jọ, ko ni mọ ọrọ ti wọn o sọ mọ nigbati o jẹ wipe, gbogbo ọrọ ti nwọn ti nsọ ati eyiti nwọn gbe ogun rẹ le ori irọ ni gbogbo rẹ ja si, awawi wo ni ki a ṣe fun ẹniti koriko pa Iya rẹ jẹ.

Otitọ de ọja, o kuta, awọn enia ko nṣe akiyesi iwa enia ki wọn to ma gbe oluware si aye ti o ni apọnle pupọ, bi o ti wu ki enia ni iwa buruku to, bi o ba ti le dun ẹnu fun enia, ti buruku, ti rere, nitoripe ọrọ ẹnu dun ro ẹfọ, agada ọwọ dun lati fi ṣa oko, irọ funfun ati ala ti ko le ṣẹ ni wọn o ma gbe gbi rẹ fun enia.

### ỌLỌLA NNAMDI ASIKIWE ṢE IKILỌ FUN AWỌN ENIA RẸ

EKO:- A gbọ wipe Ọlọla Dokita Nnamdi Asikiwe mọ wipe aṣiko idibo titun nfẹ bẹrẹ ni Ipinlẹ Ila Orun, nitorina lo ṣe ṣekilọ yi fun wọn wipe, Kere O!

WO IYOKU NI OJU EWE KẸJỌ

## Margaret Aburo Oba Gesi fi Omokunrin se Akobi

LONDON:-| Awa Oniwe Irohin Imọlẹ ba Elisabeth Ọbabinrin Gẹsi yọ ayọ orire ti aburo rẹ obinrin ti o njẹ Magaret ti o fi ọmọ Ọkunrin ṣe akọbi.



ỌMỌ ỌBA MAGARET
Iya Tunfulu na ni yi.

A tilẹ gbọ wipe, ni wọn iṣẹju kan a a y a ti aburo Ọba na bimọ ni irohin ayọ na ti lọ kakiri agbaiye ti gbogbo wọn si ndahun pe, ẹ ku ewu! Olọrun ko bani wo. Ọmọ na lo gba ipo karun lọwọ Ijoye Duke of Glọsta (Gloucester) a si tun gbọ wipe a l a f i a ni tiya tọmọ wa.

Nigbati irohin ọmọ bibi yi de, Afin lo ba Ọba binrin, nwọn ko ri aye j i ṣ ẹ fun, o ngbe oye le ẹnikan lori l a k o k o na, orukọ yi ni ọ m ọ na yio ma jẹ "Viscount Linley"

# Ọrọ Olotu

WA OLUWA NIGBATI A LE RI, PE NIGBATI O WA NI TOSI

## Iberu Oluwa ni ipinlese ogbon

Gẹgẹ bi ileri wa wipe, aki yio fi nyin silẹ nigba kan, ni alaiko gba nyin ni unoran nipa awọn iṣẹ okunkun ti o wọpọ lode isisiyi, lode toni, ati kakiri agbaiye, ko si iberu Ọlọrun lokan gbogbo ẹda enia mọ.

Iwọ ọrẹ wa ti o nka iwe yi, kini iwọ lero pe, o fa iwa ainigbagbọ si Ọlọrun yi wa.? Idahun wa ni wipe, ko si ohun meji ti o faa ju wipe, enia ni ifẹ owo ju ohun gbogbo lọ laye yi, ifẹ owo si ti jọba lọkan ọmọ ẹnia. Ati ọkunrin ati obinrin ati ọmọde ati agba, ko si ẹniti o ni suru de Ọlọrun fẹrẹ ṣe na, bi koṣe pe, eyi ti Ọlọrun ti ṣe ni nwọn nfẹ, ti nwọn si mbukata.

Nigba lailai, awọn enia a ma sara ki oruko wọn maṣe bajẹ, ṣugbọn awọn ọmọ wa ko bi kita ki oruko wọn ma bajẹ, ọgba ẹwọn ko jọ wọn loju mọ, nṣe lo tilẹ ndun mọ wọn bi ẹniti o lọ silu Oyinbo ti o si pada wa silo.

Oju ti o ba sin iya rẹ jẹ, kanna-kanna ẹba ọna ni yio yọ oju rẹ. Ijọba asiko yi, ko mọ wipe ẹnikan jẹ ọmọde gbogbo wọn ni nwọn nko da si ẹwọn panti wa ti gbogbo rẹ fi ri bẹ.? Ọmọde ko ni iberu Ọlọrun lọkan, bẹni awọn agba ko kula ofin Ọlọrun na, olukuluku nṣe bi o ti wu. Lọjọ isimi, kaka ki nwọn gba ile Ọlọrun lọ, ibi ere ibi ijo ile onje ni nwọn ma gba lọ, gbogbo inu ṣọṣi yio ṣofo gbogbo Mosalaṣi njoro, kaka ki nwọn fi ọkan yin Ọlọrun nṣe ni nwọn o bẹrẹ si fi ahọn nwọn sọ eyiti ko tọ. Ẹma kiyesi ẹni pipe ati ẹni diduro sinsin, nitoripe alafia ni ọpin iru enia bẹ. Nigbati aṣiri wọn ba tu, ti owo si buṣe lọwọ wọn nigbana ni nwọn to ma mọ ona ṣọṣi, nwọn o fi ọwọ garu oju nwọn o fi ẹsẹ kan lele, nwọn o ma wipe, Oluwa! awa ti ṣina gẹgẹbi agutan ti o sọnu, wa iranṣẹ rẹ ri Oluwa. Bi o ba si jẹ wipe Imalẹ ni, on ni yio kọkọ ji de ẹnu Mọsalaṣi ni kutu-kutu owurọ, ti yio si bẹrẹ si ja tesuba bayi wipe As-taga-furula. Awọn enia ro pe, ẹniti eda le di ni ibo koriko ni Ọlọrun, nwọn otan Ọlọrun jẹ nwọn si nfi ahọn wọn sọrọ ẹtan. Ohun ti enia mọ pe ko dara si ẹda enia tabi si Ọlọrun ti o si lọ ṣe nkan na, dajudaju Ọlọrun ẹsan yio gbẹsan. Lojọ idajọ gọngọ a s o.

Nitorina ẹnyin ọmọ iya wa ẹ ronu piwada nitori ti ijọba Ọlọrun ku si dede. Igbe ti o lọ s wa, n i eyiti a nko yi. O di ọwọ nyin.


AWỌN IWE KO ṢE MANI

IWE EGBOGI FUN ONIRURU IWOSAN;
IWE ADURA IṢEGUN AWỌN AJẸ;
IWE IFA AGBỌN-NIREGUN, IWE ITUMỌ ALA PẸLU IWADI NKAN;
IWE LILO ATI AGBARA PSALMU;

★★★ IWE ADURA TETE DA MI LOHUN;



★★★ IWE ITAN ABALAIYE ATI TI IṢẸDALẸ

KỌWE FUN IWE-ITAJA:-
OLOTU BOX 104
EBUTE METTA, NIGERIA



BERE EGBOGI JAMANI AJIDEWE TONIKI TITUN TI O ṢẸṢẸ DE TI WỌN NPE NI:-

"DYNAMIREN" TONIKI

EGBOGI AJẸBIDAN FUN AGBALAGBA ỌKUNRIN GBOGBO




Dynamiren jẹ Ojulowo Egbogi Ajidewe baunbaun ti awọn Jamani ti nṣe wa fun tita ki ogun (War) ti awọn Gẹsi pẹlu wọn to ṣẹlẹ. Lẹhin igbana a ko ri irufẹ egbogi ajidewe ti o lagbara gidigidi ti iṣẹ rẹ si daju bẹ yọn mọ ni ilu Naijiria, eyi lo mu wa ranṣẹ si awọn Ogbologbo Dọkita wa ni ilu Jamani pe ki wọn ṣe iwadi awọn elegbogi "Dynamiren" bi wọn ba si mbẹ laiye. Wọn si da esi pada wipe wọn nbẹ atipe egbogi na ti a nfẹ lọdọ wọn wa pẹlu. Eyi mu inu wa dun pupọ julọ nitoripe awọn Onibara wa mọ daju wipe kosi aṣanu ninu gbogbo egbogi wa rara. Ẹgbagbeje irufẹ rẹ wa kakiri ṣugbọn bi ti eleyi ko. Bi arẹ ara ba mu ọ, nigbakugba fun wahala tabi iṣẹ ṣiṣẹ ti o ko ba le jẹun daradara, tabi ki o ma le sun de ọkọn lọsan tabi loru tabi awọn "Iṣan ara rẹ gbogbo" ko ba ṣiṣẹ daradara arẹE-emi (breath) inu ko ba gunle daradara to nitoripe iṣẹ tabi wahala ṣiṣẹ ko "NJẸ" fun awọn ailera gbogbo wonyi ti ọjọ ori rẹ (age) ba ti kọja ọgbọn o d u n lọ si dede adọrin tabi jubẹ lọ mọ daju pe "DYNAMIREN" ni egbogi ti o nfẹ lati sọ ara rẹ di Ọtun patapata, oju rẹ a si jọlọ, ẹran ara rẹ ti o ti hunjọ yio bẹrẹ si dan pada. Ara rẹ yio ma gbe kọnkọn nigba kugba "Arẹ" nigbakugba yio salọ patapata pẹlu.

Igbadun ati Alafia yio de si ọ.

Bere egbogi na ni Ṣọbu awọn:-

NIGERIAN MEDICINE STORES
4, TINUBU STREET, LAGOS PHONE: 20278.

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street, Lagos, Nigeria**
**Phone: 22878 (Oja ita Faji)**

ADEDUN CHEMIST
4, WAKEMAN STREET, YABA PHONE: 22878

ATI NI AWỌN ṢỌBU IBADAN:-
IṢẸ OLODUMARE DISPENSARY OKE-BỌLA IBADAN.
ADEBỌGUN PATENT MEDICINE STORES
APATA AIYERAIYE STREET, ADE ỌYỌ IBADAN



## Iwo ha Nfe Igbega bi?

Fun anfani awọn ti o ngbe Eko, ti ko le mọ ile iṣẹ wa ni Mushin, ni aṣe kọ awọn apakan ninu ọja wa si Nọmba 16 Bamgbose Street Lagos, ẹnikẹni ti o ba fẹ ra ọja wa ni Eko ki o ma lọ sibẹ.

TURARI AJẸBIDAN AGBABIETU

Turari yi ko ni ẹgbẹ akoṣe fun awọn ajẹ ni, ti o ba nloo iwọ ko ni mọ a i t a ọja. Adura rẹ yio si ma a gba Awọn enia buruku aiye ko tilẹ ni lagbara lori rẹ onṣiṣẹ to igba ọna (200 ways) fun igbega ọmọ enia ni ile A i y e. (Pangolo 10/6d)

MANAGER (J. O. SHOYINKA.) c/o IROHIN IMỌLẸ 16, BAMGBOSE STREET, LAGOS.

# *ẸGBẸ IMỌLẸ AIYE*

## Aseni nse Ara re

Lati Ọwọ Abdullahi Awelẹnjẹ
No. 1, ỌMỌ ẸGBẸ IMỌLẸ AIYE.

Olotu inu mi yio dun bi o ba le gba mi laye lati fi itan mi oloyinmọmọ yi to awọn Onkawe Irohin Imọlẹ yi leti. Itan na iọ bayi:- Ni igba atijọ, ọkunrin kan wa, o si ni Iyawo kan, gbogbo ọmọ ti obinrin yi bi, patapata obinrin ni gbogbo wọn, awọn ba bẹrẹ si ṣe ajo fun obinrin na ki o le ri ọmọkunrin bi, ṣugbọn ko bi ọkunrin rara, ọkunrin yi fi ọrọ yi lọ awọn ọrẹ rẹ wọn si wi fun pe, ki o lọ fẹ obinrin miran.

Ọkunrin yi ko kọ si awọn ọrẹ rẹ lẹnu, ni o ba lọ fẹ obinrin miran l o t ọ, bi obinrin yi ti loyun, ọmọ Ọkunrin ni o si bi, eyi dun mọ baba ọmọ na ninu, depo ti o fi ni lati ra ẹran malu meji fun ayọ ọmọ na, bi eleyi ti ṣẹlẹ tan, ni ọjọ kan Iyale wa joko, o nronu wipe on ti on ti wa ni ile fun bi ogun ọdun o wa jẹ wipe Iyawo ti o de lẹnu ọdun kan si meji yi ni yio jẹ gbogbo o g u n Ọkọ on bi o ba ku, nitoripe ọmọ Iyawo yi ni yio ko gbogbo agbada nla ati gbogbo fila baba rẹ, bi o ti jẹ wipe, on nikan ni o jẹ ọkunrin ati arẹmọ baba rẹ, Iyale wa ninu ipinnu yi ni o ba loyun, lẹhin oṣu pupọ, o bimọ ọkunrin, nigbati o kọkọ bimọ yi, inu rẹ dun, ṣugbọn nigbati o tun ronu wo, ti o mọ wipe ọmọ Iyawo ju ọmọ ti on lọ, o pinnu lati pa ọmọ Iyawo yi, ki ọmọ ti rẹ le jẹ ẹniti yio jẹ ogun baba olowo yi.

Nigbati o ṣe o mu gele rẹ, o kọri sile Babalawo, dide ti o de bẹ, ti o si rojọ tan, ni o ba fun Babalawo na ni owo ṣile mẹwa, ki iṣẹ na le ya kia-kia. Lẹhin ọjọ diẹ o lọ lati lọ gba ogun rẹ, bi o ti de ọhun Babalawo ti tọju ogun na silẹ fun, ni o ba gba wale.

WO IYOKU NI OJU EWE KEJE.

## Awon Scouts lo se abewo ile Badden Powell



Ofin titun kan ti o tun ṣẹṣẹ de ni wipe, ẹnikẹni ninu Scout, ti ọjọ ori rẹ ba ti le ni ọdun mẹdogun, o ni aṣẹ lati ma wọ Ṣokoto gigun.

Awọn ti a nwo ninu aworan yi ni, awọn ti o le ni ọmọ ọdun mẹdogun ti wọn lọ bẹ ere Ọlọla Badden Powell wo ni ile rẹ. Awọn ti o wọ sokoto g i g u n ni awọn ti ọjọ ori rẹ le ni ọdun mẹdogun.

## Asoju Egbe Imole Aiye Ni Ilu Oyiubo

Lẹnulọlọyi ni Irohin kan wa pe Ọgbẹni Simeon Adegoke Fatoki ọkan ninu igi lẹhin ọgba fun ẹgbẹ Imọlẹ Aiye eyi ti a da silẹ ni ọdun ni labẹ aṣẹ iwe Irohin Imọle lo si ilu oyinbo lati tun bọ lọ kọ iṣẹ nipa bi a ti se iṣiro owo (Accountancy.)

Ọgbeni Fatoki si jẹ ọkan ninu awọn Asoju ati Olori Ẹgbẹ Imọle Aiye fun Agbegbe Eko ati Surulere, o jẹ enikan ti o wa ninu ẹniti o moju to alafia ẹgbẹ na, ohun si na, ni o ndari ẹgbẹ na ti o si tu fun akowe Agba ni imoran ohun ti o to k i o se, o jẹ ọkan ninu onigege wura nipa awọn itan aladun rẹ ti o nko sinu iwe yi, eyiti akọle rẹ njẹ Igbesi Aiye ni inu igbo ailopin. Fatoki ni eni akoko ninu ọmọ ẹgbẹ Imole Aiye ti yio ko lọ si ilu oyinbo, agbọ pe o fi ilu Eko s i le ni ọjọ aiku tise ọjọ kokandin logbọn osu ti o koja Ọkọ oju omi ni o si wọ lọ, Alo yio dara Abọ yio s u n wọn.

## Kini O mo Nipa Ile Naijiria?

(1) Tani Alagboran dun fun Ọlọla Abubakar Tafawa Balewa nipa Alafia Ilẹ Afrika?
(2) Ilu wọ ni Ilu keji ti o to bi ju lọ, ni Iha Gusu shahara
(3) Ilu wo lo fẹ dan Etu Oloro wo ni aṣalẹ Shahara?
(4) Kini orukọ ti Ilu Carthaginan njẹ tẹlẹ ri?
(5) Nibo ni wọn gbe Agogo Bower Tower si ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria?
(6) Tani asoju Ijọba Naijiria ni Ilu Oyinbo?
(7) Njẹ ibiti wọn ti tun ọsẹ Moto (Tyre) wo ba ti ba jẹ ṣe wa ni Ibadan bi? Bi o ba wa nibo ni?
(8) Lọdun wo ni ogun Owu de Opin?
(9) Nigbawo ni Ibadan di Olu Ilu Iwọ Orun Naijiria?
(10) Daruko ohun Ọgbin ti Olowo lori ju ni Ilu Ibadan ati Abẹokuta?

WO IDAHUN AWỌN IBERE WỌNYI NI OJU EWE KEJE

BERE OJULOWO EGBGOGI AWỌN FARANSE TI A NPE NI:-

"UROXAL"



Fun Itọju tabi fifọ Apo Ile Itọ Kidney - Bladder fun Ọkunrin ati Obinrin bi awọn amodi wọnyi ba nyọ ọ lẹnu Ẹhin didun eri ile tabi itọ-jijo enia, itọ riru, rukuruku Pọpọn tabi rirun, lakuregbe, Ibaradi wiwo, orunkun, ọwọ, ẹsẹ Ejika wiwu tabi riro.

Ara sisan, titobiju, aiko le gbe ara kọnkọn tabi kiakia, didaji loru nigbakugba, ati orisirisi awọn aisan tabi amodi ba wọnyi ni egbogi ajẹdan yi yio wo sàn lara rẹ ni kia kia ti alafia yio si de si ọ. Meji rẹ ko si ni Ilu Naijiria nitorina ṣora ki awọn eleru tabi awọn oni rọbirọbi ma ta orişi omiran ti ko ni lari fun ọ, maṣe gba rara o!

Owo rẹ jẹ Şile Mẹfa abọ 6/ 6d owo ọkọ sile meji abọ (2/-6d)

Bere Egbogi yi ni Şọbu awọn ṣaro ti wọn npe ni:-

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street Lagos,**
**Phone: 87228 Nigeria, (Oja ita Faji)**

# IGBESI AIYE MI NINU IGBO AILOPIN (APA 8)

Lati Owo:- Simeon Adegoke Fatoki

Olorun ko dojuti wa osi fi bakaye si wa nlau atipe ko ba oju mu wa je eyini afi nrin ni oju ona ti akosifi ma kolu ara wa ti aba pade ara. Iwo omo enia nko fe ki o huwa bi awon omugo ile aiye. Olorun Oba ti fun won ni Ola o ti fun won ni owo, ositifi alafia ara jinki won nitori eyi won ti lero pe agbara won ni, won ko mope agbara Olorun ni. Won ti gbagbe pe ko si eni ti adan wo ko le ba. Ko si si eni ti otobi julo ni odo Olorun afi eni ti ose tire. Ogbon nla gba ni emi nko e loni yi, ti Oba pade de ile aiye mo fe ki ogba omo araiye ni iya oju pe ki won ma se se Igberaga re. Rantipe igberaga ni saju iparun. Jowo Omo enia ma se gbagbe Olorun re. Olorun ti ofi ohun gbogbo jinki re, mo se gbagbe re, iwo ti oni owo mase gbekele owo re owo nfini saiylo, iwo ti obimo ere mi, omo tun nfini saiye lo, sugbon gbeke le Baba Jesu, gbekle Baba a se ohun ti onfe fun o amin !!

Enyin onikawe mi bayi ni Oba yi so ti mo si dupe fun owo re mo beresi se alaiye fun pe !!Leto emi ko ni le duro pe pupo ni ibi yi sugbon emi yio duro ti yin nibiyi fun iwonba ojo melo kan.!! Nigbati mo pari oro mi tan Oba ni ki won fun mi ni onje won si se be, mo deun mo si fi ina si koko mi mo egbadun.

Emi Oba yi ni ajo nson ni inu yara kanna, Mo pe die lodo Oba yi ki nto kuro ni ilu afoju yi. Nigbati osi di ojo ti mo ma kuro ni ilu awon afoju o yi se gudugudu meje fun mi. Won ye mi si, won si nki mi pe odigba, won tuni ilu won se mo si dupe pupo lowo won nigbati mo de arin oja won ti gbogbo won pe si ti mo si nbawon soro inu won dun ti ofi je pe won ko mo eyiti awon lese. Mo beresi bawon soro iyanju bayi pe !!Mo dupe pupo lowo Oba ilu yi ati lowo gbogbo enia ti owa nilu yi fun ayea ti eyei mi si. Mo fe ki emo lode oni pe Olorun ti oda afoju on na lo da Aro on lo da aditi, beni ni osi da eni ti ko ni labaru kan lara Ototo ni bi ase yan kadara wa ni aiye yi. Mo fe ki emope Olorun ko se ibi ri.

Mo si fe ki emo pe ore nla gba ni Olorun se fun yin ti efi wa ninu iru ipo ti ewa loni yi. Opolopo ni ode aye ntile nwa iku sugbon ako pa. Aiye tile ti su Opolopo fun idamu inu aiye sugbon ko mo ohun ti o le se Opelopo lo ti ku danu ti won ti di eni orun ti a siti gbagba won. Awon enia ko gbagbe yin rara, awon ti won si ko yin wa si ibi papa ti gbagbe pe aiye nyi. Ti obaje omo Oba Tewetagba adobale fun o, bi aiye ba yi ti gbogbo re si ba o, gbayen lo to mo eniti ofe o, gba yen loto mo awon abinu re o ni otito. Gegebi Olorun ko ti fi onje ojo yin won yin yi, Olorun ko ni binu si yin.

## MOGBAYI BABY MIXTURE

OLURANLOWO FUN AWON ABIYAMO

MOGBAYI BABY MIXTURE je ogun pataki ti a se ni ase pe fun awon Omode, ati nlo gun yi fun opolopo odun sehin pelu idaniloju fun Awon ise ribi ribi ti o ti nse.

MOGBAYI BABY MIXTURE je egbogi to dara fun igbona, iko, otutu A i p e r i, Osi Omode, jedijedi, kokoro ori Omode. O dara fun omode ti ko tete rin ati fun awon aisan miran bebe lo. O nmu omode ko ma nsun fonfon O nmu ki ehin hihu je iro run fun awon omode o sinjeki awon omode tobi, osi nmu won dan ni awo. Enyin Abiyamo, eku afojuba egbogi yi. Aran yin letipe MOGABYI BABY MIXTURE je egbogi ti ko se mani fun awon Omode I j a f a r a lewu pupo, tete lo ra tire ni le itaja Egbogi towa ni Adugbo re.

Igo kekere re je 2-6d Igo nla je 4-6d

LILO RE:- Sibi kekere lemeta lojumo

*Wholesale Distributors*

A, K. KARIMU ANJOLA & BROS

6, Balogun Street, West 34, Docemu Street
Lagos Nigeria Lagos
Phone 22515 Phone 24247




# Owo eni lafi tun iwa eni se

Bi ailowolowo ba nda o lamu, bi airomobi mba o lokan je, tabi airiese lo nyoo lenu, tabi o tile nsise na owo ise na ko duro lowo re. Tabi awon Omoraiye ko je ki o gbadun igbesi aiye re ni gbogbo ona kona.

Oko rere tabi aya rere lo nje o niya. Tabi amubo oko tabi ti aya, tabi oja ti o nta ko lo dede, tabi ohun miran lo mba o lokan je ni gbogbo ejo.

Mo daju wipe diedie lo koko bere. Ki o si tun ona re se. Kowe pelu Sile Mewa abo (10/6) pelu Sitampu oni toro (3d Stamp) fun ohun to fa ati atunse adanwo na lodo:-

AWORAWO
16, MOLEYE STREET
P. O. BOX 166 YABA - NIGERIA

# Asiwaju Awon Egbe Osise Ilu Malta.



Eniti a nwo ninu aworan yi ni ogbeni Dominic Mintoff ti ise asiwaju egbe awon osise (Labour Party) ti Ilu Malta ni arin agbami okun Mediterranean Ise ti baba re nse ti o fi ko ni Eko ni ise alase Oko Ogun. in Ogbeni Dominic ko eko re ni Malta University, o ko Ise Ile Wiwon, ati Ile Kiko o si gba Oye Ninu re.

Lodun 1947 ni nwon fi je oye Igba keji Prime Minister Ilu Malta, Li odun ti nwon dibo, ti egbe re wole ni nwon fi je oye Minister nigbati ede koyede se'e larin ati Prime Minister, lo ba binu yo ara re kuro larin egbe ti Ijoba wa lowo re.

Nigbati nwon tun dibo lo dun 1955, nigbana ni o di Minister ti gbogbo owo ilu wa nikawo re. o si je oye (Prime Minister, o tun binu fi ipo Prime Minister sile, nigbati oro on pelu Gesi ko dogba nipa Ominira.

Ofin Iselu ti won se ni odun 1947 ko te lorun nitorina, won pa ofin na re, nwon tun omiran se, nwon ni ki Mintoff ti ise Prime Minister ati awon alatako re wa rojo ninu iwadi ti won fe se fun won, totun tosi lo ko

# THE NATIONAL BANK OF NIGERIA LIMITED

## Balance Sheet as at 30th June, 1961

| 1960 £ | | £ | £ |
|---|---|---|---|
| | Capital | | |
| | Authorised : 3,250,000 Ordinary Shares of £1 each | 3,250,000 | |
| | Issued : 3,182,443 Shares | 3,182,443 | |
| | Less:- Calls in arrear | 1,913 | |
| 1,168,978 | | | 3,180,530 |
| 170,000 | Reserve Fund | | 170,000 |
| 1,416 | Profit and Loss Account Balance | | 2,113 |
| 1,340,394 | | | 3,352,643 |
| — | Future Income Tax | | 50,000 |
| 10,132,960 | Current, Deposit and other accounts | | 7,812,874 |
| 1,403,443 | Acceptances, Endorsements and other Engagements on behalf of Customers | | 2,355,354 |
| £12,876,797 | | | £13,570,871 |

Notes:

(1) The comparative figures at 30th June, 1960, have been adjusted where necessary to conform to the accounts classifications at 30th June, 1961.

(2) From the net profit for the year, as described below, the sum of £74,000 has been transferred to the credit of Provision towards Doubtful Accounts. Payment of Dividends on the Issued Shares of the Bank will be suspended until such time as, in the opinion of the Board of Directors, adequate provision for Doubtful Loans and Advances has been made. Arrears of Dividend on the 1,000,000 4% Cumulative Preference Shares of £1 each, converted during the year to ordinary shares, amount to £12,666 (net).

S. L. DUROSARO, Chairman
A. A. O. DUROSHOLA, Director

| 1960 £ | | £ | £ |
|---|---|---|---|
| 421,724 | Cash on hand and balances with the Central Bank of Nigeria | | 1,919,345 |
| 525,054 | Balances with; and cheques in course of collection on other banks | | 420,357 |
| 2,110,000 | Money at Call and Short Notice | | 920,000 |
| 549,423 | British Government Treasury Bills | | 249,793 |
| | Investments— at cost | | |
| 126,220 | Nigeria Government Securities (Market Value £126,220 - 1960 - £126,220) | 126,220 | |
| 178,990 | British Government Securities (Market Value £166,865 - 1960 - £170,821) | 178,990 | |
| 504,610 | Other (including Subsidiary Companies £165,668 - 1960 - £215,689) | 364,233 | 669,443 |
| 6,992,259 | Loans and Advances to Customers and other accounts (including Subsidiary Companies £1,289,063 - 1960 - £1,549,192), less provision towards doubtful accounts - (See note 2) | | 6,969,325 |
| 65,074 | Bank Premises, Fixtures and Motor Vehicles at cost, less depreciation | | 67,254 |
| 1,403,443 | Liabilities of Customers for Acceptances, Endorsements, and other Engagements - per contra | | 2,355,354 |
| £12,876,797 | | | £13,570,871 |

A. O. OSHINIBI, Director
E. OLU. OBASA-PORTER, Chief Accountant

### AUDITORS' REPORT

We have obtained all the informations and explanations which to the best of our knowledge and belief were necessary for the purpose of our audit. In our opinion, proper books of account have been kept by the Bank so far as appears from our examination of those books, and proper returns adequate for the purposes of our audit have been received from the Branches. We have examined the above Balance Sheet which is in agreement with the books of account and returns of the Bank. In our opinion and to the best of our information and according to the explanations given us the said Balance Sheet is properly drawn up so as to exhibit a true and correct view of the state of the affairs of the Bank at the 30th June, 1961.

Dated at Lagos this 29th day of September, 1961.

OLATUNDE AYOOLA & CO.
Chartered Accountants
THOMAS, SILVA, DAWODU & CO.
Certified Accountants
} AUDITORS

## Profit and Loss account for the year ended 30th June, 1961

| 1960 £ | | £ |
|---|---|---|
| 7,500 | Transfer towards provision for doubtful accounts | 74,000 |
| 1,000 | Stamp duty on increased Share Capital | 10,000 |
| 20,000 | Transfer to reserve fund | — |
| 65,347 | Dividends | — |
| 1,416 | Balance unappropriated - 30th June, 1961 | 2,113 |
| £95,263 | | £ 86,113 |

| 1960 £ | | £ |
|---|---|---|
| 94,242 | Net profit for the year after providing for taxation thereon (£90,647) and for taxation under provided in prior years (£66,045) but before making provision for doubtful accounts | 84,697 |
| 1,021 | Balance unappropriated - 30th June, 1960 | 1,416 |
| £ 95,263 | | £ 86,113 |

## Ijinle Imoran fun gbogbo awon Omo Enia

Lati Owo:- LATIFU B. BABALOLA.
Oludasilẹ ati Akọwe Agba Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye

MO KI gbogbo ẹnyin Onkawe Irohin Imọlẹ kakiri Agbaiye, Mo si tun ki gbogbo ẹnyin ọmọ ẹgbẹ Imọlẹ na, Ọlọrun yio ran yin lọwọ, Eledumare koni fi kọbọ meji won yin.

Bi o ba ni owo lowo, jọwọ fi ṣe ọmọ araiye lore, bi o ba si ni ipo pataki fi ṣe ọmọ araiye lore, ẹniti o ni owó loni le di alaini lọla, O n i p o pataki loni le di mẹkunnu lola.

E fi ẹsọ Jaiye, ara mi, fẹsọ jaiye ti aiye ba ja ko ṣe so, ẹnyin omo iya mi, ẹ jọwọ ẹ tẹ pa mọ iṣẹ yin, bi iṣẹ ba lowo eni gbajumọ tẹ.

Iṣẹ ni ogun iṣẹ, iṣẹ ni nje tamọ ọ ri, iṣẹ ni isaju oṣi, owo ni nje mo ba ọ tan Bi o ba ni Ọla, bẹrẹ foji agba, bi o ba si mọ 'we bẹru agbalagba, Ọla yanturu, Ọla yanturu a ma fọ oju irẹlẹ, Ẹkọ yanturu, Imọ yanturu a di eti igbọ

Ọlọrun oba ye jowọ, mase pa wa da si aidara, Jẹ ki ọ s a n wa pọn ko to wọ, Jẹ ka mu ere oko dele.

Nitorina ẹ mura si ẹkọ yio ẹnyin ọmọ ile Iwe ẹ ma fi owurọ yin ṣere ẹ ma ka Iwe yin ni gbagbogbo.

Nje emi Omọ Babalọla nrele, emi ni Ọmọ bi nko ṣiṣẹ ngo lowo, bi mo ṣiṣẹ ngo lowo Ajila ni Baba mi.

---






Ma a ka Irohin Imole losese

## Aseju Ko Dara Iparun Ni Igbehin Aseju (Apa 1)

Lati Owọ:- ỌMỌ ARIDẸGBAJU OKE ỌLA-ORO.

Mo ki awọn Oluteti silẹ gbọ ọrọ mi ti ọsẹ yi papa julọ awọn Oluka iwe Irohin Imọle, Ọlọrun kanigba lakaye yin, ọgbọn yin yio ma kun ogbọn, oye yio ma pẹlu Oye, beni imọ yio kun imọ, araiye koni riwa gbeṣe rara (Ami.)

Ẹjọwọ kiẹ gbọ ọrọ itan yi lagboye dada, itan lasan ni mi o fi ba ẹni kan kan wi rara, sugbọn itan kowa lasan, owa fun ogbọn kikọ, ati lati fi ṣe lakay kia si dẹkun aṣeyi:-so, nitori ọlọgbọn kole taomi mọ aṣọ beni Ọmoran kọle mo iye yepẹ ilẹ. Itan na lọ bayi oṣe, nigba kan, kininun kan wa ninu igbo kan, on nikan ni osije ti mbẹ ninu igbọ na, kiniun yi kofẹ ma se wahala kio ti mari onjẹ ojọ jẹ, nidi eyi, ope gbogbo awọn ẹranko ti mbẹ inuu igbo najọ lọjọ kan osi bẹrẹsi iba wọn sọrọ oni. Modupe pupọ lowọ yin fun dida ti ẹda mi lohun ni pipe ti mope yin loni, ofihan pe ẹmọ mi gẹgẹ bi Ọba yin. Ẹnyin namọ pe eni ki ise ika Ọba rora, nitori biotilejẹpe mopa die jẹ ninu yin ri, ofi han pe ẹmọ mi gẹgẹ bi Ọba. Sibesib: mo fẹ ki gbogbo wa ki se ife inu ni lati Ma payin jẹ rara.

Olukuluku ni Ọlọrun yin fun ni aojẹ tirẹ lati majẹ, gbogbo wa simọpẹ ebi kiwọnu ki ọran miran tun wọ ibe, Elomiran ninu yin amajẹ eweko asimani ite lọrun ẹlomiran ke, eso igi ni ijọ, bakanna ni ako ṣairi awọn bi Agiliti ti nwọn ma jẹ ẹran. Gẹgẹ bi ẹnyin na ti mọ ara yin ni moti ma jẹhun, niwọn bi ositi jẹ pe moni ifẹ yin.

---


GBANGBA DẸKUN! ỊKEDERE BẸWO!!




## PORAL

OLUBORI EGBOGI "IKỌ

Bi amodi "IKỌ" ti ọjọ rẹ ti pẹ tabi ti o nyọ ọ lẹnu fun nkọn bi ọdun kan tabi jubẹ lọawọn egbogi rọbi-rọbi ko le se iwosan rẹ rara, ma fi owo rẹ ṣe Ofo mọ

Bere fun egbogi awọn ara Ilu Faranse ti wọn npe ni "PORAL" ojulowo haunhaun, atimatase egbogi fun Ikọ here, Ikọ tutu, Ikọ ọna ọfun, Ikọ Igbaaiya, Ikọ lile, Ikọ" ti ọ ma mu enia tu kẹlẹbe nigbakugba lati inu "Ifun ẹa (Lungs) tabi ti o ma nmu enia ru pẹlu. Bi o ba dan Igo kan egbogi PORAL yi wo, Iwọ na yio ri iyatọ ninu ara rẹ ni kiakia, Igbaaiya tabi ọna ọfun rẹ ti o ma nho yio duro, "IKỌ" rẹ yio si san patapata, iwọ yio ma jẹun daradara iwọ o si sun fọnfọn pẹlu Alafia de.

Bere egbogi yi ati awọn orisirisi Egbogi Ikọ miran ni Ṣọbu awọn:-

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street, Lagos, Nigeria**
**Phone: 22878 (Oja ita Faji)**

ATI NI AWỌN ṢỌBU IBADAN:-
IṢẸ OLODUMARE DISPENSARY OKE-BỌLA IBADAN.
ADEBOGUN PATENT MEDICINE STORES
APATA AIYERAIYE STREET, ADE ỌYỌ IBADA

### EYI NI IDAHUN AWON IBERE TO WA NI OJU EWE KETA.

(1) Dr. K. O. Mbadiwe (2) Ibadan.
(3) Faranse. (4) Tunisian. (5) Ibadan.
(6) Ogbeni Abudu Maliki (7) Beni, Oke Ado.
(8) 1825 (9) 1952 (10) CoCoa.

## KERE O! AKIYESI PATAKI

Awa na le jeri wipe ojulowo haunhaun Egbogi gidi ni LEOPILLS, Awa na nlo ni ilu Gold Coast (Ankara) Ghana pelu, meji re kosi ninu gbogbo orișirișii Egbogi kakiri Ilu Naijiria.




### Irohin kakiri Igboro Ilu Eko

Bena ni ewe ni Igboro Ilu Eko, Irohin ti l o wa lenu gbogbo enia. tomode ti agba ni asiko yi ti won si fi șe oro ati oriu larin ara won je nipa ti Egbogi Jamani olokiki yi ti won npeni LEOPILLS.

Imoran awon Dokita Oyinbo ti won șe Iwadi Egbogi LEOPILLS yi kan so wipe bi o ti lagbara to, ti oje ojulowo giriki ati atamatase fun iwosan JEDIJEDI bi o ti wu ki ojo re pe to bena ni awon le tun le fi owo soya tabi șe ileri fun gbogbo awon ti amodi tabi aisan bi Ako Inarun. Lakuregbe, Eje didu lara, Arun Edoki Iju, Igbesise, tabi Aikori Igbonse dede, Inurirun nigbakugba Ara wiwo, Esanri, Ehin didun, Oju si san tabi aiko riran kedere. Kokoro buruku lara, Osi inu Onigba meji. ati orișirișii arun miran gbogbo pelu "Wipe" won yio ri alafia ni kiakia ti won ba nlo egbogi LEOPILLS nitoripe a si tun ma tun 'eje șe lara enia nipa siso di otun patapata.

ȘE IRANTI PE ALAFIA NI OGUN ORO
IJAFARA SI LEWU PELU (POSTAGE 1/9d)

Egbogi Leopills:— Igo nla șile mefa pere ni,
Igo kekere șile meta pere ni.

Bere ojulowo Egbogi omiran fun orișirișii amodi ti o ba fe ni Șobu awon:-

Waterloo Medicine stores
8, Palm Church Street, P. O. Box 333. Lagos Nigeria Phone: 22878. ati pelu ni șobu ara binrin Mrs C. O. Babajide near Health Office Ibadan ati ni Abimbola Medicine Stores B29 Okesha Street, Ilesha Bisale Medicine Stores. British & Foreign Medicine (Dealer) S. W. 6/458 AGBOJO STREET IBADAN, N.

AKIYESI:- Ri daju gbangba wipe Șobu ti won nta lo gbe ranse lo ra, bi beko awon elomiran yio fi ERU lo ta adamodi tabi orișii omiran fun o o, ma șe gba rara

---

### OBERE LATI OJU EWE KETA

Bi o ti dele omo iyawo ko si nile omo tire lo si wa ni ita to nsere nigbati o dele o ro Iyawo re titi ti oni tohun fi jeki o se onje nigbati ose ewa na tan.

WO IYOKU NI OJU EWE KEJO

## Petepete T'ana ni Popa

Lati Owo:- "AIYEKO OTO"
IWE SI OLOLA M. A. O. OLANREWAJU.

Mo woye nisisiyi pe gbogbo omo Ile Igbomina Offa ati Ekiti ni won ti fi ohun sokan pe awon ti fi ara mo lati gba Ipinle fun Igbomina, Offa, ati Ekiti laipe ojo.

Bi a ba woye dada, ao ri wipe Ile Igbomina, Offa ati Ekiti ti wa labe ase Oba Ilorin oto Ogorun Odun o le adota sehin Ha! ese, oti Oyinbo alawo funfun ti ile wa ti wa labe won lati nkan bi Ogorun odun sehin, igbati o ya awon enia wa parapo won gba Ominira lowo Geesi kini ti Ilorin ti wa je ti Ile Igbomina Offa ati Ekiti ko fi le gba ara won sile labe S u l u Gambari?

O to akoko fun wa lati ro ori ara wa wo bi a ba si woye ao ri wipe ko tile dara loju rara pe ki ile Igbomina Offa ati Ekiti wa labe awon Ilorin. Bi e ba ye itan Ilorin wo, ao ri wipe Ilorin ko jagun ko ile Igbomina leru ri bi won ba si fe so itan pe awon ti jagun ko ilu Offa tele ri, oye ki a ran Gambari leti wipe kise agbara Ilorin ni o fi ko Offa leru won ko si so fun mi ti wipe Ilorin jagun ko ile Ekiti ri. Nitori idi eyi nigbati o ti han gbangba wipe kise pe Ilorin ko ile wa leru ni, ese ti ao wa ma sin won titi Aiyeraiye?.

Mo mo daju wipe awa ara ni a nda Ipinle ti a fe gba duro nitoripe kosi eyiti o kan Sulu Gambari nibe. Awa ni enu wa ko logba ti anba ara wa ja ijakadi nipa egbe Olomi ni yio wole tabi Olope ni yio wole oro oselu lo da Ominira ile Igbomina Offa ati Ekiti duro. A mo wipe ile wa Naijiria ti gba Ominiaa, șugbon ki omo Ile Igbomina Offa ati Ekiti mase ka ara won pelu awon Naijiria to gba ominira Ominira. ko si nibi kankan fun Igbomina Offa ati Ekiti to ju wipe ki won gba Ipinle tiwon lo! Șugbon nisisiyi ti ile Offa Igbomina ati Ekiti ti fi ara mo egbe O l o m i oro buse, Ipinle wa ti de tan.

WO IYOKU LOJU EWE KEJO

---

## Nigerian Ports Authority

PERMANENT PORT PASSES

APAPA QUAY, CUSTOMS QUAY

The public are hereby notified that all Permanent Passes (Blue) authorising the holders to enter any or all the Authority's quays at Lagos, will cease to be valid after 31st December, 1961.

New passes, which will be of a different colour, will be obtainable on or after 15th November, 1961, by completing and submitting an application form, together with two passport size photographs, to the Dock Superintendent at Apapa Quay or at Customs Quay, from whom application forms may be obtained.

Permanent Port Passes will only be issued to those persons whose business or duty necessitates their frequent entry into the Port Area (s) concerned. Where there is doubt, applicants may be called upon to supply proof of their need for frequent entry to the Port Area (s).

Persons requiring a pass to enter more than one quay need only make one application upon which, if the application is approved, the necessary Permanent Port Pass permitting the holder to enter the required area (s) will be issued.

Applications will only be accepted from employers on behalf of their employees and passes will be issued to the employers for handing to their staff. Individual applications from employees will not be accepted neither will passes be handed to employees.

Employers are reminded that passes issued to their staff are to be returned to the Authority when such staff leave their services or their duties cease to warrant regular entry into the Port Area (s)

BAYO KEHINDE
Secretary to the Authority

N. P. A. Notice No. 640
24th October, 1961.

